# Ẹ ṣeré papọ̀

Kíkọ́ bí a ṣe n pín nnkan, ṣe nnkan ní tẹ̀léntẹ̀lé, bánisọ̀rọ̀, wà ní ìbalẹ̀ara, àti ṣíṣe ọ̀rẹ́ pẹlu awọn míràn jẹ́ àwọn ìṣe tí eniyan nílò fún igbe-aye ṣugbọn tí ó maa n gba asiko lati kọ awọn ìṣe yii! O lè ran ọmọ rẹ lọwọ lati kọ nipa awọn ìṣe pataki yii nipa ṣìṣeré papọ̀, tabi kí o ṣètò ọjọ́ ìṣerépọ̀ pẹlu awọn ọ̀rẹ́ tabi awọn mọlẹbí, bóyá ní ojúkojú tabi lori FaceTime tabi WhatsApp.



**Olobó oníràwọ̀**
Gbogbo ọmọdé ló yàtọ̀! Ara àwọn kan yá gágá wọ́n sì ní ìgbóyà ju àwọn ẹlòmíràn – máṣe ṣe àfiwé kí o má sì ṣe dààmú – ìwọ ni o mọ ọmọ rẹ jùlọ nítorí náà fún wọn ní àtìlẹ́yìn àti ìwúrí tí ó nílò.

**Njẹ́ o mọ̀** pé kíkọ́ bí a ti nbá àwọn ẹlòmíràn ṣeré ṣe pàtàkì fún ìdàgbàsókè ti ara, ti àwùjọ àti ti ìrònú àwọn ọmọdé? Ó tún nràn wọ́n lọ́wọ́ láti kọ́ pé àwọn ẹlòmíràn ní èrò àti ìmọ̀lara tí ó yàtọ̀ sí tiwọn.




**Olobó oníràwọ̀**
Ṣe kóríyá fún ọmọ rẹ kí o sì fún u ní ìdánilójú láti gbé ìgbóyà rẹ̀ ró bí ó ti bẹ̀rẹ̀ síí ní àwọn ọ̀rẹ́ tirẹ̀.

Àwọn ọmọdé nṣeré ní onírúurú ọ̀nà tó pọ̀:

- Ṣíṣeré fúnra wọn
- Wíwo bí àwọn ọmọdé míràn tí nṣeré
- Bíbá àwọn míràn ṣeré; ṣíṣe irú nnkan kan náà ṣùgbọ́n láì dara pọ̀ mọ́ ara wọn
- Fífi ìfẹ́ hàn sí eré tí àwọn míràn nṣe kí wọ́n si bẹ̀rẹ̀ sí í bá ara wọn sọ̀rọ̀
- Bíbá ara wọn ṣeré, ní ọ̀pọ̀ ìgbà ní ìsọ̀rí kéréje

